# Rò Ó Kó O Tó Fín Ara

Ṣé ó ti ṣe ẹ́ rí bíi kíwọ náà fín ara? Kó o tó ṣe ohunkóhun, ronú nípa nǹkan wọ̀nyí:

## KÍ LÈRÒ RẸ?

**Báwo ló ṣe máa ń rí lójú ẹ kéèyàn fín ara?**

- **Ó dáa gan-an**
- **Kò dáa rára**
- **Ó sinmi lórí ìdí tó fi ṣe é tàbí ohun tó fín sára**
- **Ó sinmi lórí ibi tó fín in sí**
- **Ó sinmi lórí bó ṣe tóbi tó**



www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

# RONÚ LÓRÍ OHUN TÍ ÌWÉ MÍMỌ́ SỌ

**Ìdí tí mo fi fẹ́ fín ara ni pé** _____

**Ẹsẹ Ìwé Mímọ́:** "Ẹ kò sì gbọ́dọ̀ kọ ara yín lábẹ nítorí ọkàn tí ó ti di olóògbé, ẹ kò sì gbọ́dọ̀ fín àmì sí ara yín."—**Léfítíkù 19:28.**

**BẸẸ̀ NI ÀBÍ BẸẸ̀ KỌ́: Àwọn Kristẹni gbọ́dọ̀ máa tẹ̀ lé òfin tí Ọlọ́run fún àwọn ọmọ Ísírẹ́lì yẹn.**

**Ìdáhùn:** **BẸẸ̀ KỌ́.**

Àwọn Kristẹni ò tẹ̀ lé òfin Mósè mọ́. (Hébérù 7:18-22) Àmọ́ ohun tó wà nínú ìwé Léfítíkù 19:28 jẹ́ ká mọ ojú tí Ọlọ́run fi wo fífín ara. Àwọn tó ń gbé láwọn orílẹ̀-èdè tó yí Ísírẹ́lì ká máa ń fín orúkọ tàbí àmì òrìṣà tí wọ́n ń sìn sára.

**Kí lo rò pé ó fà á tí Ọlọ́run ò fi fẹ́ kí àwọn ọmọ Ísírẹ́lì fín ara?**

_____

_____

_____

**Àwọn ìgbà wo ni kò ní bójú mu rárá fún Kristẹni kan láti fín ara?**

_____

_____

_____



www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

**Ẹsẹ Ìwé Mímọ́:** “Gbogbo Ìwé Mímọ́ ni Ọlọ́run mí sí, ó sì ṣàǹfàání fún kíkọ́ni, fún fífi ìbáwí tọ́ni sọ́nà, fún mímú àwọn nǹkan tọ́, fún bíbániwí nínú òdodo, kí ènìyàn Ọlọ́run lè pegedé ní kíkún, tí a mú gbára dì pátápátá fún iṣẹ́ rere gbogbo.”**—2 Tímótì 3:16, 17.**

**Ẹsẹ Ìwé Mímọ́:** “Ẹni tí ó bá ń wo inú òfin pípé tí í ṣe ti òmìnira ní àwòfín, tí ó sì tẹpẹlẹ mọ́ ọn, ẹni yìí, nítorí tí kò di olùgbọ́ tí ń gbàgbé, bí kò ṣe olùṣe iṣẹ́ náà, yóò láyọ̀ nínú ṣíṣe é.” **—Jákọ́bù 1:25.**

**Ṣé o rò pé èèyàn lè fín ọ̀rọ̀ tó dáa sára, bí àpẹẹrẹ, ọ̀rọ̀ inú ẹsẹ Bíbélì kan?**

- **Bẹẹ̀ ni, torí pé** _____
- **Bẹẹ̀ kọ́, torí pé** _____

**Ká sòótọ́, kí ló dáa jù tá a lè ṣe tá a bá fẹ́ máa rántí àwọn àṣẹ àti ìlànà inú Bíbélì?**

_____

_____

_____

**Àwọn ọ̀nà míì wo ló dáa tá a lè máa fi rántí àwọn tá a nífẹẹ́?**

_____

_____

_____

“Ká sọ pé o fún ẹni kan lẹ́bùn tó dáa, tí onítọ̀hún wá mú ọ̀dà dúdú, tó sì fi kọ nǹkan sí gbogbo ara rẹ̀, báwo ló ṣe máa rí lára ẹ? Bó ṣe máa rí lára Ẹni tó dá wa nìyẹn tá a bá fín ara wa.” **—Anna.**


www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

Ó rẹwà lójú tèmi.
Ṣebí oge ni mo fẹ́ ṣe,
èmi ni mo sì ni ara mi.

**Ẹsẹ Ìwé Mímọ́:** “Kí ọ̀ṣọ́ yín má sì jẹ́ ti irun dídì lóde ara àti ti fífi àwọn ohun ọ̀ṣọ́ wúrà sára tàbí ti wíwọ àwọn ẹ̀wù àwọ̀lékè, ṣùgbọ́n kí ó jẹ́ ẹni ìkọ̀kọ̀ ti ọkàn-ayà nínú aṣọ ọ̀ṣọ́ tí kò lè díbàjẹ́ ti ẹ̀mí ìṣejẹ́ẹ́jẹẹ́ àti ti ìwà tútù, èyí tí ó níye lórí gidigidi lójú Ọlọ́run.” **—1 Pétérù 3:3, 4.**

**Ẹsẹ Ìwé Mímọ́:** “Kí sì ni ohun tí Jèhófà ń béèrè láti ọ̀dọ̀ rẹ bí kò ṣe pé kí o ṣe ìdájọ́ òdodo, kí o sì nífẹẹ́ inú rere, kí o sì jẹ́ ẹni tí ó mẹ̀tọ́mọ̀wà ní bíbá Ọlọ́run rẹ rìn!”**—Míkà 6:8.**

**Kí lo rò pé ó fà á tí Bíbélì fi sọ pé ó ṣe pàtàkì pé ká mẹ̀tọ́mọ̀wà tàbí ká máa ṣe nǹkan níwọ̀n?**

_____

_____

## Ipa wo ni ìrísí rẹ lè ní lórí àwọn ẹlòmíì?

| ÀWỌN ÈÈYÀN<br>Ka 2 Kọ́ríńtì 6:3. | ÀWỌN ỌRẸ́ RẸ<br>Ka 1 Kọ́ríńtì 10:31-33. | ỌLỌ́RUN TÓ Ò Ń SÌN<br>Ka Róòmù 12:1. |
|---|---|---|
| **Kí nìdí tí ojú táwọn èèyàn fi ń wò ẹ́ fi ṣe pàtàkì?** | **Tí mo bá lọ fín ara, ipa wo ló máa ní lórí àwọn míì?** | **Báwo ni ohun tó ò ń ṣe sí ara rẹ ṣe kan Ọlọ́run?** |
| _____ | _____ | _____ |
| _____ | _____ | _____ |
| _____ | _____ | _____ |
| _____ | _____ | _____ |



www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania